The chief Secretary to the Govmnt


# EKO AKETE

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makennu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No 304. SATURDAY, DECEMBER 8 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



19 DEC. 1928 LAGOS

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi latlai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Aṣe, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san [illegible] arun mi silẹ.


A. Dem. f.

Akin Adesigbin


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr. Earl S. Sloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON,
Road, London. E.C.
RED ONLY BY
CORPORATED)
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
Office. BOSTON
in United States of America
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson L^TD
Clerkenwell R^D London.
England

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko | Ilu miran ni Nigeria | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹta | 6/- | 9/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si E.T.O.

# GBOHUN-GBOHUN.

### OGIDAN OLOLA IJU, B'ONILE NI'LE.

A gbọ pe pakute kan ti Ọdẹ kan dẹ fun awọn ẹranko loko rẹ ni apa igbo didi Ọjọ, mu Ẹkun kan tobẹ ti ẹkun fi yọ ekanna rẹ lati ho irin pakute na eyiti a sọpe o bu lọwọ ti ẹjẹ rẹ si fi ngan. Lọgan ẹkun yi ti bẹrẹ si ẹjẹ ara rẹ lati mu titi o fi fi bẹ ṣe ara rẹ leṣe ki oloko to wa ba nibẹ ti iyẹn si fi yinbọn fun.

### ỌNA APAPA D'ỌNA IPATA.

Ogidinleje awọn wonpari ni a sọpe nwọn mbẹ lọna Apapa nibiti nwọn ngbe lugọ de awọn enia papa ti nwọn ba mọ pe awọn enia na ti gbowo loṣu ti nwọn yio si bẹrẹ si lepa wọn lati ṣe wọn lọṣẹ.

---

## DUNIYAN—LABARI.

[ Lati ọwọ Kekere-Awo. ]

### KERUBU ATI SERAFU.

A gbọ wipe awọn ẹgbẹ yi fi iwe akiyesi si ode wipe ki ẹnikẹni wa ba awon ṣe ipade adura ni Alakoro ni alẹ ọjọ Alamisi ijẹwa, ọjọ 29 oṣu *November* to pari yi, fun Ọba *King* Alaiyeluwa, nipa amudi rẹ. Adura tiwa ni wipe ki Ọlorun ṣe amudi na ni fifuyẹ, ki o si gba ajo awọn ẹgbẹ yi ọ, amin—aṣẹ !

### JAMAT AHMADIA.

Awọn apakan Jamat Ahmadia yio ṣe "Basa" ni ile Ṣukuru won ti o mbẹ ni Ẹlẹgbata, ni ọla *Sunday*, nwọn yio si bẹrẹ si ta ọjọ won ni dede agogo mẹjọ-abọ ni abẹ alaga Ọgbẹni Bakare King ati awọn isangbere bi Sanni Adewale ati Buhari Animaṣawun.

### IKU MBẸ ALIMUTU.

Ọpọlọpọ anu lo ṣe wa nigbati a gbọ ti iku ọdọmọkunrin ti o njẹ Thomas ni ọjọ Jimọ ijẹsan ti nṣe ọjọ ti oṣu *November* pari gan, ọdọmọkunrin na ni a gbọ wipe o nṣiṣẹ fun oyinbo Faranse ni ṣọbu ti o mbẹ ni oju Ọlọbun, nwọn si rohin gẹgẹbi awọn oyinbo rẹ ti kanu iku ọdọmọkunrin na to. A ki awọn obi, ẹni ati awọn oyinbo rẹ, papa awọn ẹgbẹ "Ansarud-deen" kekere ku oya na, Oluwa ki o dẹlẹ fun u.—amin.

### FRANCIS WEY.

Bẹni tẹdun-tẹdun ọkan ni a tun fi gbọ ti ọfọ Ọgbẹni Francis Wey loru mọju ọjọ *Wednesday* ijọkanla ti nṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu *November* to pari yi. A ki ẹbi, aya ati ọmọ ku ọfọ, ki Oluwa gbe e si afẹfẹ rere, a si tun tọrọ fun aburo Ologbe yi na, gẹgẹbi ti wey, ẹniti o ṣe alaisi ni *September* 1926, ki Oluwa fi wọn han arawọn ninu iboji ti o tutu ninu.

### ILU NSUN NDAN?

Ominu nkọ wa pupọ nipa aisan ti o nja ni ilu yi ni aseko yi, kakiri li a gbọ wipe ti Kiriyo ti Imale nṣe adura firifiri, sibẹsibẹ ko i ti dabi eyiti o dawọ duro loju wa, nitorina li a ti ṣe sọ wipe ominu nkọ wa, irufẹ aisan ilu bayi ko ye wa tọ, ni iwọn igbati o jẹ wipe lati lailai ni ajakalẹ-arun ti ma nja ti nwọn ba si ti tẹ ọwọ adura, lẹsẹkanna ti yio si ti dawọ duro, ṣugbọn a ko mọ itumọ eyiti o nja yi, ohun ti o ba si fa sababi rẹ, o yẹ ki ẹnyin ariran tabi oloye wariko si i, nitori ogun fẹ de mutaku, ki Oluwa dawọ rẹ duro fun wa, nile-loke—amin.

### SAKARA NFẸ BOLẸ.

O dabi ẹnipe a ngbọ wipe nwọn nra awọn Oni-sakara mu bi o ba jẹ jẹbẹ, iba ma dara julọ, a ko ṣai ngbọ wipe ilu-sakara na ko dara papa ni aseko ti ajakalẹ-arun ba mbẹ ni ilu bayi.

---

No. A.C, 257/41.

The Editor "Eko Akete"

Notification has been received that H.M.A.S. "Canberra" will visit Lagos on the morning of Sunday the 23rd of December, leaving on the morning of the 24th, in the course of her voyage from England to Australia.

## IDAJỌ ẸJỌ AKARIGBO ATI JIMBO APENỌ.

**Ni ọjọ Thursday ijọ kejilelogun oṣu November 1928, niwaju ọlọla Adajọ Meroyn Lawrence Tew.**

*Suit No. 155 of 1927.*

WILLIAM ADEDOYIN II.
(The Akarigbo of Ijẹbu Rẹmọ)
*versus*
JIMBO APENA.

Ẹniti o pe ẹjọ yi ni Oloye Akarigbo ti Ijẹbu Rẹmọ o si ngbe Shagamu n i apakan awọn agbegbe wa, to si fẹ ki wọn mọ ati lati sọ wipe on lo ni aṣẹ lori ilẹ ti owa ni Ipakodo ni apakan ilu Ikorodu ninu ilu.

Ẹniti wọn pe ni ẹjọ ni Apena, ẹri pupọ ni wọn jẹ nipa ti tumọ oye yi ati irufẹ nkan ti oye na wa fun ati iṣẹ ẹniti amọ ni Apena, fun nipa ẹjọ yi irufẹ ẹri bayi oni lati ri ṣe ninu ẹjọ yi nipa wipe nigbati ẹniti o pe ẹjọ wipe oye Apena jẹ oye ẹniti oni ọwọ nipa iwa rẹ, ati pe ko si iran Akarigbo kan, gẹgẹ bi ẹniti ape ni ẹjọ pe ara rẹ ni lati jẹ oye irufẹ eyi, oye yi ko ni nkan kan ṣe pẹlu ilu na ati pe ẹniti wọn pe ni ẹjọ si gba bẹ.

Ẹri nipa itan lailai nipa awọn to tẹ ilẹ yi do, ni lati wa lati ẹnu awọn ẹniti o mọ igba iwaṣẹ. Itan ẹniti wọn pe ni ẹjọ ni pe ilẹ na jẹ ilẹ ti Kuyelu, ẹniti o kọkọ jẹ oye Akarigbo, Kuyelu si bi ọmọ mẹrin ọ k u n r i n, awọn w ọ n y i lo pin ilẹ fun ti wọn si nlo, ati pe ilẹ ti P a k o d o yi lo fun ọkan ninu awọn mẹrin eyiti orukọ rẹ njẹ Ṣẹkunmade. Koyẹlu fi Shagamu ṣe ile, o si mu ọwọ kuro ni ilẹ Ikorodu, ṣugbọn eyikeyi ninu awọn to jẹ oye Akarigbo lẹhin na, ni wọn nfi ọla fun lati iran awọn ọmọ rẹ gẹgẹ bi onilẹ tabi ọba. Ẹniti osi pe ẹjọ yi gba wipe otọ ni ni wọn pin Pakodo fun Ṣhẹkumade fun lilo tirẹ ati awọn ọmọ rẹ ṣugbọn ki ṣe pe fun iran yẹn nikan tabi wipe Akarigbo ko ni aṣẹ lori rẹ mọ. Ilẹ yi gẹgẹ bi oti wi ilẹ oye ni, ti on ni lati pa aṣẹ le ẹgẹ bi ipo oye on; o jẹ ẹtọ lati tan idi oro yi wo, gẹgẹ bi ọna ti ẹniti o pe ẹjọ fi ni ti on ni ati pe Lọya Kayode to wa fun ẹuiti wọn pe ni ẹjọ sọ ninu ẹrọ rẹ wipe, ẹniti o pe ẹjọ nsọ wipe ilẹ na ti awọn ẹbi on ni, nipa iba ọgbọn tirẹ ati awọn ti wọn ti jẹ ṣiwaju rẹ, gẹgẹ bi ọna ti on tọ yi, eyi a jẹ ọrọ ti kosi nipa nkan ti ko ye enia to ṣe bi on mọ nipa itumọ eyiti ẹniti ope ẹjọ sọ, wipe oye yi ti awon ẹbi on nikan ni; Ẹniti ope ẹjọ sọpe baba ẹniti on pe ni ẹjọ, Saogu, o jẹ alejo lati Ishẹri leti Abẹokuta. To si fi ara rẹ si abẹ Akarigbo to si fun ni ilẹ ni Ipakodo. Ṣugbọn gbogbo ẹri Kotu ta ko eyi wipe irọ ati ofifo ni ọrọ na, Emi ni itẹlọrun wipe bi a ba wo ọrọ na wo lati iṣẹdalẹ bi awọn ẹni wọn yi, ẹniti ape ni ẹjọ yi jẹ ọmọ Shekumade ọmọ Koyelu, ati pe itan nipa Ishẹ oni idi tirẹ ni otito wipe ọmọbinrin to jẹ iran ẹniti wọn pe ni ẹjọ fẹ tabi gbe ara Ishẹri kan ni iyawo, eyi to si jẹ wipe ẹniti wọn pe ni ẹjọ si jẹri si, ẹniti wọn pe ni on ni tabi iyekan lati ọjọ na. Bi Koyelu ba fi Shekumade si Ipakodo gẹgẹ bi ọrọ ti Jimbo sọ nipa itan na, eyiti mo gbagbọ, njẹ on papa ni aṣẹ to fi silẹ lori ilẹ tabi on papa parẹ wipe ti Shekumade ni, on papa ni itẹlọrun si ilẹ ti eti Shagamn nibiti on papa do si, eyi jẹ nkan ti ko kun mi loju yala Koyelu tabi ọmọ rẹ da ọja si Pakodc.

Awọn apakan sọ wipe on papa ngbe eti Ebute fun igba diẹ ko to pada lọ si Shagamu, ati pe wọn le ti le e da ọja yi nigba na.

Eyiti ani lati fi si ero ni ale sọpe lati inu ero wa lori otitọ ti wọn fi han wa, ati imọlẹ diẹ ti a le fi si lori itan ẹjọ miran to fi ara pẹ irufẹ eyi ti wọn sọ.

Ko si tabi-tabi wipe Akarigbo ti Ijebu Rẹmọ wipe awọn Ikorodn gba gẹgẹ bi onilẹ tabi oluwa wọn. Ati pe Idajọ Akarigbo pẹlu awọn Ikorodn ko ba pọju bẹ lọ ko to di wipe itan aye-baye ti wọn pa yi to fi Ikorodu fun ilu to si la Shagamu fun Igberiko. Ko to to igba na awọn ilu mejeji yi wa ni abẹ Ajẹlẹ oyinbo to si fi Shagamu ṣe budo. Akarigbo sọ pe gẹgẹ bi Olotu tabi Alaṣẹ tabi alabojuto on ti mu ọwọ on kuro ni ori Ikorodu ṣugbọn kini ati on ati awọn aṣaju on wọn ko ye paṣẹ lori ile yi.

O yẹ ka yẹ awọn ẹjọ t wọn ti ṣe lori ilẹ ni Pakodo wo, to si wa siwaju Kotu ilẹ yi lati iwọn ọdun mẹdọgbọn sẹhin ninu eyikeyi ninu awọn ẹjọ yi Jimbo Apena ko ṣe alai ni ninu rẹ, ni ọdun 1903 Jimbo Apena pe Da Silva kan ni ẹjọ lati gba ilẹ ti on papa ti fun Da Silva yi ri ati pe Da Silva yi ti pa ipinnu ti wọn ṣe rẹ. osi ṣe on to lodi si ipinnu na, Jimbo Apena jare ẹjọ yi, ti ko si wipe wọn ro ẹjọ kan tabi darukọ Akarigbo sinu rẹ. ninu ẹri rẹ o sọ wipe Ilẹ na ti Baba on ni, on si ni agbara lati fun enikẹni fun lilo, ti wọn ba si lo tan ki wọn fi silẹ ṣugbọn wọn ko gbọdọ gbe ta. Ni ọdun 1918 Ọdunsi Kọsọko kan pe Jimbo Apena ni ẹjọ o sọ wipe ki owa sọ bo ti ṣe ni apakan ninu ilẹ na. Jimbo Apena gẹgẹ bi Adajọ Pennington ti la, o si sọ itan na lati ori Koyelu ati pe Kosọko jẹbi ẹjọ rẹ, ni ipari idajọ na ninu iwe ti wọn ko si, Adajọ na sọ pe—Jimbo A p e n a fi ara rẹ silẹ fun Akarigbo Shagamu lati wa le on jade kuro lori ilẹ na, ṣugbon ẹnikẹni ko ṣe nkankan fun, nitori na ẹniti o pe ẹjọ ko ni ẹtọ kankan sọri ilẹ yi. Ṣugbọn emi ko sọ nkan kan nipa bi Jimbo Apena ti ṣe ni. Lọya Moore fun Akarigbo duro lori idajọ wipe bi Akarigbo ti ṣe ni ẹtọ wa lori idajọ ọdun kẹwa ọhun. gẹrẹ ko to de ori oye. Ṣugbọn emi ko mọ apa ibo ni ẹri yi gbe wa ki Adajọ to wi bẹ ninu ero rẹ. ko to di ti Akarigbo ẹniti ojẹ wipe owa ninu ẹjọ, ati pe lori eyi ọrọ na jẹ eyi ti ko si to si dun leti ṣugbọn ti ko ni idi.

Ninu ẹjọ kẹta eyiti wọn rọ ni ọdun 1923 niwaju Adajọ Vander Meulen Jimbo Apena pe ẹjọ fun ara rẹ ati ẹbi gbogbogbo ti Saogu (ologbe) wipe ki wọn le tu ilẹ ti Akintolu ta danu, ẹniti ojẹ Balogun Ikorodu eyiti wọn ta fun Lawani kole. Jimbo Apena tun ro ẹjọ rẹ bakanna, gẹgẹ bi ti ẹjọ yi. Eyi ti o sọ pe Emi ni olotu gbogbo Pakodo, bi ẹnikẹni ba fẹ ilẹ lati lo wọn ni lati wa si ọdọ mi, ṣugbọn Adajọ ninu idajọ rẹ sọ pe, on ro wipe imọlẹ wa ninu ọrọ na, wipe Koyelu pin awọn ilẹ wọnyi, ti eyi ti won nro ẹjọ le wa ninu rẹ, ninu awọn ọmọ mẹrin ni Sẹkumade wa, ati ilẹ ti wọn mọ ni Pakodo wa pẹlu.

*(Koi pari).*

## OṢU AWỌN ALAPARỌ LE E!

Ninu oṣu *December* ti a bẹrẹ ni ọjọ *Saturday* ti o kọja ni oṣu awọn alaparọ obinrin ti wọn ki nṣiṣẹ bẹrẹ, tirẹ ni nwọn wọ ni Ẹhingbẹti ko si ọja kọbọ ti wọn nlọ ra, ọmọ-lomọ ti ẹru Ọlọrun duro fun, tabi eyiti gbogbo ẹbi fi ile duro fun ni wọn nyọ olugbongbo dani lati parọ, awọn obinrin miran ti ọkọ wọn ko jẹ ki wọn jade, nṣe ni wọn nja rukẹ nile bi iso kijipa, ti nwọn si nba ọkọ wọn sọ, ko ba kun gbe ọrọ, wipe ṣe ti S.C.I.N nibi ni mo fẹ de mi o ṣa ni koja ibẹ, ọkọ rẹ mọ wipe ti owo ṣiṣẹ ninu ẹjẹ ara ile on lọwa, o si mọ dajudaju wipe ti S.C.I.N. to wi yi, yio ṣe bẹ de ti Fairley ngbọ, aṣẹ ti ọkọ rẹ pa fun ọ ni yẹn, ọpọlọpọ awọn nkan buruku wọnyi 'wọn a ni awọn nwa ọja ọdun ra kiri, ẹranko rẹ ko ma jẹun ana sun, nitori ko si kọbọ ni ọwọ rẹ, nwọn a wa fi mọṣaṣi leri sondoko o di Ẹhingbẹti nwọn a ni awọn nlọ wo bi awọn ba ma ri ṣẹ—nwọn a lọ ni ataro titi di alẹ, awọn miran nṣe egbogi dani ki on le ri ẹru ko, njẹ iwọ alarede ti ẹ gbe-yawo ti o ju ọdun meji lọ, ti dia rẹ ko gbọ tirẹ mọ, njẹ iwọ ko mọ pe awọn alaparọ wọnyi ni, kini iwọ le ṣe si irufẹ nkan bẹ ni eyiti ọdun npari lọ bayi, ko si, aiya fi ko tẹwọ bọ adura si Ọlọrun ninu eyiti ọdun 1928 nlọ, ki ọdun 1929 ma ri bẹ fun ọ! ngbọ iwọ ọmọ-onibi-niran to gbẹ panṣaga dani ti gbogbo awọn ẹbi rẹ sọ fun ọ titi ti o ko gbọ, ti o ni ko ni ṣe bẹ mọ, ko ṣe bẹ lo de owo rẹ, iwọ Dani yi, o ye ipa kun losun ko mọ bi igbesi aiye rẹ ti ma ri lọdun 1929, iwo ko mọ pe panṣaga wọnyi nwọn nwa ibi ifi ajaku rọ si ni, idaji ni arọ, jẹjẹ mi mo nlọ, panṣaga ma pami, ṣe iyẹn bi iwọ papa ko ba pa ararẹ, mo sọ eyi fun itiju nyin, nitori ẹnyin panṣaga oju ijọba wa ni ara nyin wipe ki ẹ ma lọ wa iṣẹ ṣe—owo papa dani ilu, ofifo ni ẹ nba kiri.

## "APPEAL LỌYA ZIZER NI ILU OYINBO."

Gbogbo nyin lẹ o mọ tabi kẹ gbọ ni ijelo wipe ijọba da Lọya yi duro fun igba diẹ, lẹhinna o bẹrẹ iṣẹ rẹ pada, ṣugbọn gbogbo nyin ẹ ṣebi wipe bẹ ni ẹjọ na ku si, ṣugbọn akere-koro nyin tun gbe ẹjọ na lọ siwaju adajọ mẹta nihin, pabo ni gbogbo rẹ, o tun bere aṣẹ lati gbe lọ si ilu oyinbo, awọn ijọba ilẹ yi tun fun, ṣugbọn sibẹ-sibẹ o wa gbe ẹjọ na lọ *Privy Council* ki nwọn ba on gbọ ẹjọ on, ṣugbọn gbogbo rẹ nlọ bakanna ni ẹjọ rẹ tun jẹbi ni ilu oyinbo wipe ohun ti wọn ti da fun ni ilẹ yi iyẹn ni awọn fi aṣẹ si, nitorina eyi a fi nyin ni ọkan balẹ wipe ko si ayederu ni ilu oyinbo, awọn a ma nyọ ipin loju nwọn a fi han oju wipe nkan to ṣe ko dara. Lọya Jonathan Cclluis Zizer yio wa so agbejẹ mọdi wipe iṣẹ ni ni abojuto, oju kan ni ada ni iyẹn ni ti ofin, abamọ ko si ninu ofin—Akere-koro idajọ yi koro janyinjanyin ṣugbọn iwọ a fi kọgbọn fun ọjọ miran ọjọ rere.

## ỌPA ỌBA.

Ẹ ba wa wa ọlọpa si adugbo wọnyi: Kakawa ati Broad Street, ati Ọdunlami ati Broad Street, Joseph Street ati Broad Street, Prison Street ati Broad Street, nitori ewu mọto tun awọn enia wa—Ki Ijọba ki o pẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

---

## ORI V.

## IGBOIYA.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KEJI.

Nigbati iwe ti a npe ni *Norum Organon* jade, ibosi gbojikan, nwọn ni yio da "rugudu" silẹ, yio da "Ilu ru" yio sin "din agbara ẹsin ku"; Ọkurin kan ti a npe ni Dr. Henry Stubbe (ẹniti a ba ti gbo oruko rẹ rara, bikoṣe nitori ọrọ yi) si kọ iwe kan ti o fi tako ọna ẹkọ ọgbọn titun yi, o bu gbogbo awọn ti o ntọpinpin ọna ọgbọn, o ni "nwọn ṣoju bi oju *Bacon*." Ko tilẹ ku *Royal Society* silẹ pẹlu, o ni "a ntọpinpin ọna ọgbọn yio da ẹsin Kristi ru."

Nwọn ṣe inu-ni-bini si awọn ti o gba ẹkọ Copernicus, nwọn pe wọn ni Keferi, nwọn pe Kepler ni aladamọ. o ni, "nitoripe mo tẹle ọna ti mo ro pe o ba ọrọ Ọlọrun mu." Ani Newton enia jẹjẹ, ẹni-re, ẹniti Bishop Bunet sọpe ko si ẹniti ọkan rẹ mọ to tirẹ—ẹniti inu rẹ dara bi inu ọmọ-titun—ani Newton kan yi na ni nwọn sun ni

ęsun pe "o ni ti Ọlọrun bawo", nitoripe on ni o kọ ri idi ofin pe lala ti o roke ilę ni nbọ; irufę ęsun kanna ni nwọn si tun fi sun Franklin, nitoripe o la idi bi ara ti ję fun ni.

Awọn Jew yọ Spinoza, ara wọn, ninu ijọ, nitoripe nwọn ro pe ọna ękọ ọgbọn rę yapa si ęsin; lęhin eyi diẹ loṣi ku, lęhin eyi, ki janduku enia kan pa a nidi ọrọ kanna yi. Gbọin-gbọin ni ọkan Spinoza duro titi de opin, o ku yępęrę sinu iṣę.

Nwọn kọ ọna ękọ Ọgbọn Descartes, nwọn ni yio sọ awọn ęniti o ba gba ękọ na di alai-lęsin; nwọn ni ękọ Locke yio mu enia gba pe ko si ohun ti a npe ni ęmi; ęwę. ni asiko tiwa, nwọn sun Dr. Buckland, W. Sedgwick ati awọn ijimi miran ti o ję ijimi lọna ękọ ọgbọn ti ohun ti o wa nisalę ninu ilę, lęsun pe nwọn nyi eyiti iwe ifihan kọ nipa bi ilę aiye ti ri po. Ni gasikia, ko daju pe ęnikan wadi ọna ọgbọn nipa ti Orun, Oṣupa ati awọn Irawọ, nipa ti ęda awọn nkan ti a nri, tabi nipa ti ęda enia ati ęranko, ki o ma si awọn kan ti nwọn ro pe ọdọ awọn ni ọgbọn pękun si ti nwọn a si tako oluwarę, ti nwọn a sọ pe ọna ọgbọn bayi yio sọ enia di keferi.

Awọn ijimi ọlọgbọn miran, bi a ko tilę sun wọn lęsun pe ękọ wọn lodi si ęsin, a ko gai sọ aidara si wọn lara lọna iṣę wọn ati lọna miran.

Nigbati iwe Dr Hawey, nipa bi ęję ti nwọn ninu ara, jade, ko ri iṣę ṣe tobę mọ, awọn oniṣegun ęgbe rę si pe e ni were. John Hunter ni "ki nto le yanri iba awọn iṣę rere ti mo ṣe, idiwọ ti mo ri ati ijakadi ti mo ja ko kere." Nigbati Sir Charles Bell nṣe ayan a nwadi ti agbajọ awọn ọgbọn pataki ti a ni ioni nipa bi ęda enia ati ti ęranko ti ri, o kọwe si orę rę kan, o ni; "Bi nko ba kuṣę ni, ti ko ba si si ti ọpọlọpọ nkan ibinu ti mo nri ni, kini inu mi iba ti ma dun to!"

On na papa si ṣe akiyesi pe bi iwe on, nipa ọna ọgbọn ti o nwadi yi, ti njade ni ọkọkan bęni on ko ri iṣę ṣe to ti lailai mọ.

Bayi ni a ri i pe ilọsiwaju ọgbọn, lọnakọna, eyiti o tubọ mu ni mọ si i nipa awọn ohun ti nbę loke (ọrun), ni ilę ati nipa awa na papa, ję eyiti awọn ęni nla atijọ nọwo nọra, ti nwọn gbe iku ta si, awọn ęniti o ję pe biotiwu ki awọn ęgbę wọn lasiko wọn, tako wọn, ki nwọn bu wọn to, loni wọn wa ninu awọn enia ti awọn ọlọgbọn aiye ngba fun, ti nwọn si nfi inu didun wari fun.

Bęni ikorira ainidi ti nwọn korira awọn ọlgọbọn ijọun, ko ṣai ję ękọ fun awa enia tode isisiyi. O kọ wa lati ma korira awọn ti kọ ba gba tiwa, bi o ba ṣe pe awọn enia bę ba fi suru wadi ọna ti nwọn nto, ti ero wọn ba ję atọkan wa, ti nwọn ba si nfi otitọ ati aifoya sọ eyiti ọkan wọn pe lọna.

Plato ni o sọ pe, "Aiye ję iwe ti Ọlọrun kọ si awa ęda;" ki a ko iwe na ki o si ye ni yeke-yeke ko ni ṣe enia ti o ę ori rę pe ni nkan afi ki o mu tubọ mọ bi agbara Ọlọrun ti to, ki o mu tubọ mọ bi ọgbọn Rę ti to, ki o si mu tubọ ṣọpę fun ore Rę.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## ITAN ALADE ỌBA IPĘRU NI JĘBU RĘMỌ.

***O bęrę lati inu iwe wa ọsę to kọja.***

Nigbana ni ara Iperu kọ fun wọn, ti wọn si wipe bi o ba ję pe Ipęru ni ęnyin ma gba lọ si ogun wọn ni o ya ni ati ọdọ ara Ipęru nigbana ni ogun ara Ode fi rę ni aseko ọlọla Ọba Shibọnioye ni owa ni ori oye nigbana, dajudaju ọmọ Awujalę ọlọlo li o mu Ade Ọba si Ode, odepeju ki ṣe ati Ile Ifę rara ọmọ Ękęwa Olu ni Oba Ode nṣe, ọmọ Ękęta Olu ni Ọba Alapęru nṣe, ni Ọba Alapęru ni Ijębu Ode ara ilu męta ni awọn ipilęṣę ara Ipęru ti wọn tę Ipęru do. Gbogbo awọn ara ilu męteta yi ọmọ Alade ni wọn ni ati ilu wọn wa nitorina mo ro pe mo sọ sinu Eko Akete ni ọdun 1926 pe, Ọba 16 ni ọmọ Oduduwa ni Ile Ifę ti awọn Baba wọn sore nigba Ijimiji tabi ni kutu Emi sọ pe ęni ti o mọ oruko wọn titi ọsę kan ki o sọ ka gbọ orukọ awọn Ọba męrindinlogun na nitori emi sọ orukọ wọn kọja idaji. Ęlęda awọn ọlọla Ajayi Jomu ati Ęlęda ọlọla Ọpęlę L. Apena yio ba oluwarę ro ęjọ ati Işęşe Ipęru.

## IROHIN ARIYAN-JIYAN ITAN ẸLẸPẸ IJẸBU-RẸMỌ.

Awọn ọlọla sọ wipe ẹru Ẹlẹpẹ ni Akẹsan nṣe-nkọ awa ko le jiyan pe bẹni a ko si le sọ pe bẹkọ rara, nitori ibiti ara Ipẹru gbe nna oja ni on ni nwọn ko gbọdọ kọ ile sibẹ rara gẹgẹ bi adehun ti awọn Baba so pe nwọn ti ba Akẹsan Balẹ ọja ṣe wipe on ko fẹ ki ẹnikẹni kọle si tosi on rara oni nitori Ifa ti awọn Babalawo da fun on ni on ṣe sọ bẹ titi di oni ẹnikẹni ko jẹ kọle sibiti wọn gbe sin oku Akẹsan Balẹ oja si jẹ enia Ẹlẹpẹ nitorina ni awọn ara Ipẹru ṣe ngbe ija Ẹlẹpẹ nigbati awọn ara ilu Ọlatigbelu nfẹ gba ade Ẹlẹpẹ titi awọn ara Ipẹru ko ni iyẹn titi awọn aṣọde Ọba Alapẹru fi yinbọn ni nkan bi ọdun 1905 tabi jubẹlọ ti nwọn pa ole ni oju ode Mr. S. A. Anọbaọgọ, Ipẹru ti awọn Ijọba Igẹsi wa ko wọn de Shagamu a ti sọ ọrọ na ti wọn ko jẹ ti o jẹ oran ade Ẹlẹpẹ ni awọn Mr. Nobody dasilẹ ni Shagamu ara Ipẹru ko jẹ ki wọn le gba ade Ẹlẹpẹ nigbana rara Eko ni wọn dẹ gbe wa ṣe ẹjọ Aṣọde ọba Alapẹru na Mr. Oshibanjọ ni orukọ rẹ. Nitori na ki Ọlọrun Jọwọ pẹlu mi.

Ni a ti ọjọ ti wọn ti sọ wipe nwọn ti tẹ ilẹ Rẹmọ do ogun ko ṣi ara Ipẹru ni idi pada ri rara titi di oni Ipẹru ko ni orilẹ ti ogun si wọn rara. Ara Ipẹru ni owo diẹ nwọn tun ni suru diẹ, awọn ara Ipẹru si fẹran awọn alejo pupọ nitori gbajumọ enia ni nwọn jẹ larin ilẹ Rẹmọ bi a ba ri awọn oyinbo oniṣowo ti o ba mu owo lọ si bẹ awọn aṣọde Ọba Alapẹru ko ni jẹki awọn ole tabi awọn ọlọṣa ko nkan wọn rara.

Shagamu ṣa ni awọn ole ti gbe sefu lọ ti wọn ko ri titi di oni, nigbati Ọlọla Ọba Okunpẹ ati Ọlọla Ọba Adenugba ṣe awo ti wọn ja; ni Ọba Alapẹru fi ranṣẹ pe ki wọn wa gba ade ni owọ Ẹlẹpẹ ni Ipẹru ni Church C.M.S. Ipẹru, ni D. O. Ajẹlẹ Isagamu ni o wa gba ade na ni ọwọ Ẹlẹpẹ Ọlọla Adenugba titi di oni, Nitorina Ilu Ẹlẹpẹ kere ni mo rope nwọn fi ure Ẹlẹpẹ jẹ, a gbọ dajudaju pe ọlọla Ọba Ẹlẹpẹ, Ọba Alade ni gẹgẹ bi emi ti gbọ ni lailai ri, bi awa ko ba fẹ gba ẹṣẹ; eyi ti emi gbọ ni ẹnu awọn baba nla wa ni iyẹn o.

Ki Ọlọrun jọwọ jẹki o dara fun gbogbo wa, amin. Emi ni ọmọ Ọba Alapẹru, Ọlọla Ọba Ipẹru.

## IROHIN ODO-OGBOLU.

A gbọ dajudaju ni ati odo Ogbolu pe Mr. Emmanuel Ogunbẹkun odi oku ọmọ rẹ mọ kẹkẹ lọ si Ijebu Ode nigbati wolewole ara ago so fun pe ki o lọ ko ọti wa fun on ti o lọ sọ fun Ọba wọn ti Ọba wọn tun sọ fun pe ki o tun lọ ko ọti wa fun on bakana nigbana ni wọn wa di oku ọmọ ọjọ marun mọ kẹkẹ odi ọdọ oyinbo Ajẹlẹ D. O. ni Ijẹbu Ode.

A dupẹ pupọ lọwọ D. O. Ajẹlẹ Ijẹbu Ode nigbati Mr. E. O. Ogunbẹkun ro ẹjọ pe wọn ko jẹki on sinku ọmọ on odi ijarun ti wọn bi ọmọ na ti on ba lọ sinku ọmọ na nkọ wọn le wa sọ fun nyin pe oku alagba ni niwaju nyin, nigbana ni D. O. kilọ fun wọn daradara ti o sọ fun Mr. E. Ogunbẹkun pe ki o lọ sin oku ọmọ rẹ nigbana ni o ri aye lati wa Iyawo rẹ Madam Mary Ritan ninu iyẹn ki Ọlọrun ma jẹki awọn enia wọnyi ri iru rẹ mọ lailai, Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,
J. A. O. SHOMADE.

INA WỌLE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**_EKO AKETE_**

EKO, SATURDAY, DECEMBER 8, 1928.

## OGUNLỌGỌ OYINBO NWỌLẸ YI NWỌN RI IṢẸ ṢE, KINI TI ENIA DUDU TI JẸ?

Bi pupọ enia ti nsọ to yi pe iṣẹ ko si ni igboro Eko fun awọn ti nwọn nfẹ sibẹsibẹ ko si esi ti o yẹ ki Ijọba fi si ibere Ọgbẹni Ọlọla Moore ni Ajọ Igbimọ Agofin ti nwọn ṣe koja yi nipa pe bi Ijọba ko mọ pe ọgọrọ enia lo mbẹ ni Eko lairi ọkan ṣe'kan, bikoṣe esi pe Ijọba ni awọn mo bẹ, ṣugbọn ewo ni awọn yio ṣe, ki ẹniti ko ba ri iṣẹ ṣe gba ona oko lọ roko.

Ẹnyin ilu, ẹ ko wa ri iwa agunla, aguntẹtẹ ti o mbẹ ninu idahun yi bi? O di Oyinbo melo ni a ri ti nwọn nrin kakiri ode nibi lalairi ọkan ṣe'kan; ọsọsẹ kọ ni ọkọ nde silẹ yi lati ilu Ọba ti nwọn si nwa ogunlọgọ Oyinbo wa sibi fun iṣẹ, irufẹ iṣẹ wo ni Ijọba ko fi nwọn si tan; ẹ lọ si Apapa, ẹ lọ si Ijọra, ẹ lọ si Yaba, ẹ lọ si okun, ẹ o ri bi awọn Oyinbo ti ngba yin ninu orișirisi iṣẹ ti a fi fun wọn. Oyinbo gba iṣẹ titi nwọn gba iṣẹ Fọlefọle, nitotọ awọn Enia Dudu pupọ mbẹ ninu awọn iṣẹ wọnyi, ṣugbọn ọpọlọpọ ninu awọn ara wa ti nwọn ko ri ṣe lo pọ ju, ati bu okele ṣe arẹ ẹlomiran, o ha ri bẹ fun Oyinbo kọkan bi? Agbẹdọ.

Aṣa miran ti a tun gbọ pe o ngbilẹ larin awọn Ọga iṣẹ ni ibi iṣẹ miran tun mu ki airi iṣẹ ṣe yi tubọ pọ si gidigidi, a gbọ pe o jẹ aṣa awọn Ọga iṣẹ wọnyi lati ma sọ fun ẹnikẹni ti o ba wa iṣẹ wa si ọdọ wọn pe ki oluwarẹ "ko obi" fun awọn, eyi ni pe ki oluwarẹ lọ ba wọn wa owo, ki nwọn to ba ṣe ki oluwarẹ ki o le ri iṣẹ ṣe: a tilẹ sọ pe ninu awọn Ọga iṣẹ wọnyi nbu iye owo ti ẹniti o ba nṣe ajo iṣẹ lọna bayi ni lati mu wa fun wọn. A gbọ pe irufẹ iwa bẹ wọpọ larin t'oyinbo t'enia dudu ni ibi iṣẹ miran.

Loju wa, iwa aibikita ti Ijọba nhu ni ọna bayi si didin inira ilu ku nipa dida iṣẹ silẹ fun awọn alairi ṣe ko jẹ ohun ti o wọ rara, Oyinbo melo ni o mbẹ loni ti nwọn njoko sile fun airi iṣe ṣe, bi a si sọ nipa ti ọna awọn Oyinbo Onișowo, ko si ọkan ninu wọn ti awọn ki ṣai fun ẹgbẹ wọn alawọ funfun ni iṣẹ ṣe, kilo ha si ti ṣe ti o fi jẹ pe eyi fi nri bẹ.

Ijọba sa wipe ki awọn ti ko ba ri iṣẹ ṣe mu ona oko pon, elo ni Ijọba le fun irufẹ awọn enia alairi ṣe wọnyi ninu owo Ijọba lati fi da'ko ati lati fi ma gbọ bukata rẹ: nitotọ ti ara ẹni la nko l'esu, bi ko ba ṣe bẹ ni kini iba jẹ ki Ijọba fun awọn Oniwe-irohin Ilu Ọba ni £2,547. 10s. 0d. fun inawo Akanṣe Iwe-irohin ti a sọ pe nwọn ṣe fun *West Africa* ti nwọn si sọrọ *Nigeria* sinu rẹ; njẹ bi enia dudu kan ba kọwe si Ijọba pe ki nwọn ṣe iranwọ owo fun on fun Iwe Itan *Nigeria* kan ti on ṣẹṣẹ nṣe lati tẹ, Ijọba yio da oluwarẹ lohun bi? Ndao. Eyiyi ko to ẹko fun gbogbo awa enia dudu bi, pe inu asingba ni a ṣi wa. Kaka ki a bẹrẹ si mọ eyi bẹ, ṣe ọtẹ ni a ngbe si ara wa, ti awọn Oyinbo nrẹrin.

O dọwọ nyin o, amulele!!!

---

## ẸNITI O KUN 'LẸ TO GBIN IKA, ORI ONI 'KA NI IKA IHU LE.

(APA KEJI)

**LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.**

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ l'oji,

O pọ lọpọlọpọ ti o jẹ wipe ko ni iṣẹ meji ti nwọn nfi gbogbo aiyan wọn ro, bikoṣe iwa-ika.

Ọna pupọ ni ẹlomiran ngba fi huwa ika si ọmọ-ẹnikeji rẹ, nwọn nṣe ẹlomiran ni ika nipa iṣẹ, nipa obirin, nipa owo ati nipa ohun omiran.

A ha le șiro melo-melo Ọmọ-Anabi Adamọ ti nwọn nṣe ni 'ka dano nipa inunibini nipa arankan ati oniruru iwa gbogbo bẹ-bẹ ti ko sunwọn ṣugbọn irufẹ awọn ẹni bẹ gbagbe Oluwa, bi o ti wu ki o ri ẹlẹṣẹ kan ki yio lọ lai jiya ẹṣẹ.

Ko si imọran ti a le gba awọn oni-ika nisisiyi ju wipe ki nwọn lọ ronupiwada, ki nwọn si ṣe iranti pe iku mbẹ Alimutu.

Dajudaju ko si ẹniti yio ju si aiye, bi a ti nsun ti a nji ni ọjọ ori wa ndikun, ṣugbọn ẹmi awọn oniwa buburu le saba ngun gbọrọ, ti nwọn o si ma ro wipe bi ẹmi wọn ti gun jẹ ohun anfani pataki fun wọn, ye! ti Olodumare ko ri bi o ti npe e awe.

Bi ẹnikan ba nhuwa ika tabi bi iru awọn iwa buburu gbogbo bawonni, Oluwa yio fi ọwọ lẹran yio ma wo ibiti oluwarẹ yio ṣe de, tobẹ ti oluwarẹ yio fi ni itẹlorun si ori ohun gbogbo ti o ba nṣe, inu on papa yio si ma dun, boya so 'kuro ti o ti ṣe si ikọkọ iyara, yio ma tanjẹ ẹ, pe sa tubọ mura, on ti sọ oluwarẹ ro; Asarayilu ko le ri i gbe ṣe ohunkohun, ṣugbọn nigbati ọjọ na ba de, ibiti oluwarẹ gbe ṣe so kurọ si, dajudaju kiakia lo ma juwe ibẹ.

Nigbana ni Asarayilu yio wa yọ ọjọ rẹ wayi pe iwọ ti o ti so on rọ, on de o ku ibiti yio wọ fun on loni, anu yio ṣe ni pe boya lo ma le fi ọwọ juwe debi ẹnu, nigbana ni Asarayilu yio wa sọ wipe o ti pẹ ti o ti nṣe ti on ti nmọ oluwarẹ loju, on pẹlu oluwarẹ dikarewa loni, nitori nigbati nwọn ba wọ gidigbo lojọ na, dajudaju so 'kurọ ni lati di omi, nigbati a ba gbọ gbi pe ẹnikan ṣubu, o ni lati jẹ Asarayilu lo da oluwarẹ, nigbana ni ariwo ma wa ta.

Boya nigbati Asarayilu ba yọ kumọ rẹ de lojọ kan fun ẹlomiran ti o nhuwa ika lati jiṣẹ, boya oluwarẹ le ri ohun ti o le gba a la lọjọ ti aseko ba to, a bere ni—mẹmba!

Awa ni igbagbọ pe Oniṣegun tabi Alufa na koi ti ji ti ọrun wa aiye ti yio da oluwarẹ duro, ti o ba si ti ji ti ọrun wa aiye njẹ ki ọkan balẹ fun awọn oniwa buburu gbogbo ti Anabi Yisa tabi Anabi Mọmọdu fi ko ni pe a ni lati jinna si lati hu, lojọ ti ọjọ ba pe.

Bi ẹlomiran ba gba owo loṣu tabi ti o ba ti ni bi elo kan lowọ, o di wipe ki o ma sure ọmọ ẹnikeji rẹ kiri ojule Babalawo tabi ile Alufa, awọn Babalawo tabi Alufa ti o le ma ṣe iṣẹ aidara bẹ, ni ero wipe on le ri ọrun wọ? Bi o tilẹ le ri ọrun wọ, nibo lo ma ru iṣẹ rẹ wọ? Ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti awọn ti nwọn mbẹ won lowẹ, ti awọn na yio si ma ro wipe ṣe iṣẹ owo wọn ni awọn nṣe, ko si eyiti o kan awọn daniudanin nibẹ.

Apẹrẹ ti aiye ni a ni lati ma fi kọ ọgbọn, nisisiyi ki ole kan lọ ji nkan, ki o si lọ gbe fun ẹnikan pamọ pe ki o ba on toju rẹ fun igba diẹ, yala nwọn ba ara wọn ṣe adehun tabi ti nwọn ko ni adehun, bi ọwọ ba tẹ ole nyẹn, ti o ba di tulasi lati gbe ohun ti o ji jade, dajudaju ọran ni lati kan ẹniti o gbe fun dani, okan ninu apẹrẹ ti aiye ni mo fi han nyin yi, dajudaju bẹ li o si mbẹ ni orun, aiyafi bi Ọrọ Ọlọrun ba tun lọ yipada ṣa lo ya ku.

Nitoto a ko de ọrun bọ, a koi si ti gburo ẹnikan ri, pe o ti ọrun bọ debi ti o fi le gbe ogun ohun ti o ni lati ṣẹlẹ lọjọ Igbende ka 'ri, ṣugbọn awa nsọrọ nipa ọrọ ti awọn Ojiṣẹ Oluwa fi kọ ni ninu awọn Iwe mimọ ti o jẹ ọrọ Ọlọrun.

Bi ẹnikan ba si sọ wuyẹ lọkan rẹ wipe oku ọrọ li a sọ yi, a le ni igbagbọ si pe oluwarẹ fun ara rẹ li o ṣe ẹda rẹ, ti ko si si ifoiya ki ifoiya kan fun un mọ gbere ati titi lai.

Iwọ amokunkun ṣole bi Ọba aiye o ri o ti Ọrun ri Ọ o, nitorina ki olukuluku lọ tọju iwa rẹ.

"Boṣe 're, bo o ṣe 're O o b'Ọlọrun nibẹ."

## ẸSẸ NṢE GIRIGIRI LODE GIRIGIRI.

Pẹlu bi a ti nke to, ti a nyan to yi, nipa Ajakalẹ-arun ilu wa, sibẹsibẹ o tubọ ngadabu ni bi aṣa awọn alaṣa.

Njẹ ko ha yẹ ki a sorikodo bayi? Nitori eyi ma nfẹ rekọja ala loju wa.

Ọpọlọpọ Ajakalẹ-arun lo ti nja loju wa ati loju awọn baba wa ti nwọn fi npitan fun wa, irufẹ Ajakalẹ-arun ti o ti bẹrẹ ni ilu yi lati ọdun kẹrin ọdun 1924, eyiti awọn Dokita Ọba npe ni Arun Ekute yi jẹ ohun abami loju wa, nipa bi o ti mba ilu fira yi.

Ọpọlọpọ igba ni a ti fi sọrọ Ajakalẹ-arun yi ri, pẹlu ẹbẹ ọkan, ti o ba si ṣe yio buka, nipa eyi a ranti igba ti awọn Dokita Ọba nsọ wipe arun na ṣẹ nkase ni ilu, ṣugbọn nigbati o ba tun ṣe yio tun gbi naya bi ina Idunmọta, yio si tun ma horọ bi ologbo oko.

A ko ṣai ranti nigbati arun yi kọkọ be gaja wọ 'lu lati Oko-Awo ti o si npa enia gburu, ọpọlọpọ iṣẹ ni awọn Dokita Ọba ṣe si, ti Ijọba si nnawori iribi nipa rẹ eyiti nwọn ko ṣai nna nipa rẹ di bi a ti nwi yi, a ko ṣai ranti awọn Alufa Ṣọṣi ati ti Mọṣalaṣi ati awọn Aborisa ti olukuluku wọn nṣe etutu lọna tirẹ, ti Ọlọrun si ngba ajo na diẹdiẹ, ṣugbọn nigbati o ba tun ṣe arun na yio tun gbija, yio tun di ogun ohun ti o ni lati tun gbe awọn ẹniti o nbojuto ilera-ilu si iṣẹ, ti o lagbara daradara.

Ni ọdun 1925, Arun na buku diẹ loju wa, nigbati o si tun di ni ọdun 1926, Arun yi tun de, bi eyiti o sọ wipe, mo de nibo ni ẹ o wọ fun mi, ọdun 1928 yi ni ko tilẹ wa ṣe patapata, Oluwa ma ṣanu wa kẹ, ohun ti a ba ṣe ma jọwọ ki O tori awọn ẹni rere di wa silẹ, ki O mu Ajakalẹ-arun yi kuro nibi gbogbo ti o ba gbe wa—Amin.

Ki iṣe ni ilu yi nikan, bẹ bi a ba gbọ wipe o nkọṣẹ fa kakiri igbereko, tabi ni ilu miran.

Loju wa ọwọ ti o tun gbe ni aseko yi ki iṣe bi igbati enia i ba sọ wipe Erin ka ọwọ ija leri gbọnran lati ja, wẹrẹwẹrẹ ni o, dabi ẹnipe arun na nja, o si le ju oni papanleke lọ, sibẹsibẹ na

awọn Alabojuto-ilera ko baye bẹni nwọn ko wo, ki a ba ni bayo nwọn ko mura si to gẹgẹ bi atẹhinwa ni.

Arun na ko ipaiya pupọ ba ọpọlọpọ enia tobẹ ti o jẹ wipe bi ẹnikan ba ti fi ọrun kọlẹ wẹrẹ nisisiyi ti oluwarẹ si ṣe bẹ ku, o di wipe ki awọn onile na bọ si inu ipaiya titi Oyinbo ma wa fi wo oku na, o di igba ti nwọn ba gbe oku fun wọn, ki ọkan ẹlomiran to balẹ, kilo nja ẹlomiran laiya ti o fẹrẹ le ma ṣu sara? Nitori ki nwọn ma gan wọn lọ si Ikoyi lati lọ ṣe itọju wọn, ki arun na ma ba ran wọn.

Ṣugbon ju gbogbo rẹ lọ, a fẹ ki Oluwa dawọ arun na duro fun wa, ki Oluwa le mu ipaiya na kuro fun wa.

Wayi o ki a wa ba awa ara wa; ohun ti a fẹ sọ ni wipe, ẹ jẹki a sorikodo daradara nipa Ajakalẹ-arun yi bi o tilẹ jẹ wipe awọn Alufa Kiriyo ati ti Imale nṣe Ajo pupọ ti awọn Abọriṣa papa si nṣe etutu, sibẹsibẹ o dabi ẹnipe, ẹniti o ba, lo ba fun ẹlomiran, ṣugbọn ki a ranti pe ina ni arun yi jẹ ko ṣe fi si ori orule sun, bi ko ba si oye rẹ ti a tun ri lati bi ojọ melo sẹhin titi di isisiyi, nipa ọfọ ti o nṣẹ kakiri ti o si njẹ ti arun ode yi, a ko le ni ero lati sọ nipa rẹ loni.

Ẹ jẹki a tunbọ mura gidigidi nitori eyi ko ye ni to, ọdọmode nku pupọ ju lọkunrin ati lobinrin, nitorina li a tun ṣe sọ wipe enia kole fi ina si ori orule sun, ko si ohun irira ti o tun ju eyi lọ, ni iwọn igbati ilu ba kun fun ọfọ, bi a tilẹ ri ẹniti o le maṣe ohun ayọ, sibẹsibẹ ko le dabi alara.

A ko i ti pari ọrọ yi loni, ṣugbọn, adura atọkan wa ti a ri loyẹ ti a fẹ fun nyin loni lo mbẹ ni isalẹ yi, a ni lati ma ṣe e larọ, lọsan ati lalẹ, boya Oluwa yio gbọ yio si gba adura. Ki a ma wi bayi pe:—

> "Oluwa Iwọ ni Ẹlẹda ọrun ati aiye ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ awa jẹ aguntan Rẹ Iwọ ni alanu julọ ati oludariji ẹṣẹ ohun gbogbo ko ṣehin rẹ ri, gẹgẹbi o si ti jẹ wipe ko si agbara kan ti a ni niwaju Rẹ a bẹ ọ pẹlu Ọla Rẹ ki o ma ṣai mu ajakalẹ-arun ti o nja nile, loko, jake-jado yi lọ si aye rẹ fun wa, ki o si dawa si labẹ anu ati ikẹ ati igẹ Rẹ, maṣe binu si wa gẹgẹ bi iwa wa, a mbẹ Ọ ki o moju kuro fun wa nitori awọn ẹni-rere Rẹ amin"

Awọn Imale le ṣeadura na larin igbati nwọn ba nkirun wọn, awọn Kiriyo ẹwẹ si le ṣe tiwọn ni aseko ti olukuluku wọn ba mba Ọlọrun wọn sọrọ, ki a si ma ṣe pẹlu ibanujẹ ọkan lori ikunlẹ ti o ni irẹlẹ julọ, ẹ jẹki a si ma dan eyi wo na to-to o!

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

## *Olusakin's Column.*

### Mr. J. T. Nelson Cole Re-Appointed as Revising Barrister.

His Excellency the Officer Administering the Government has re-appointed Mr. J. T. Nelson Cole, Barrister-at-Law, as the Revising Barrister for the Municipal Area of Lagos.—Congratulations.

### Mr. J. C. Zizer's Appeal.

*Dismissed by Privy Council.*

London, Saturday.

The Privy Council has dismissed but without cost the appeal of the Nigerian Barrister against an order of the Supreme Court of Nigeria suspending him from practising for three months—*Reuter.*

The case referred to above is obviously the appeal of Mr. J. C. Zizer against the judgment of the Supreme Court suspending him for three months for professional misconduct—*The Nigerian Daily Times 3/12/28.*

### Sir Otto Beit's Generosity.

**Donation to King Edward's Hospital Fund.**

London, Nov. 30.

Sir Otto Beit has offered £50,000 to the King Edward's Hospital Fund for London for the purchase of radium for use in the hospitals. In accepting the gift the Funds officials state that it will enable immediate relief to numerous patients who now have to wait their turn to share the benefits of the limited supply of radium now available.

Sir Otto Beit who has large business interests in South Africa has given much financial assistance to scientific research. Last May he contributed £10,000 to the British Red Cross Society to help establish a Chinic for the treatment of rheumatic diseases. He followed this with £3,474 to complete the £40,000 required for this purpose.

### Forthcoming Marriage.

A marriage has been arranged and will take place between Miss Christiana Abọsẹde Agbebi, daughter of Mr. Deniyi Agbebi of Ebute Metta, and Mr. Gabriel Adebisi Fọlawẹwọ Cole, of 4, Alade Lane, Lagos, at St. Jude's Church, Ebute Metta, on Tuesday, the 8th January, 1929, at 10.30 a.m.

Ẹ ku ipamọ ki Oluwa m'ọjọ ro.

KING'S COLLEGE, LAGOS.
**Founder's Day.**

Saturday, December 8, 1928, at 3.30 p.m.
CRICKET—School *versus* Old Boys
TEA at 4 p.m.
Monday, December 10, CONCERT at 8 p.m.

---

THE ARRIVAL OF HON. DR. C. C. ADENIYI-JONES.

By the Steamer *R.M.M.L.* "*Accra*" which arrived this port on Wednesday afternoon, the 5th instant. The Hon. Dr. C. C. Adeniyi-Jones was among the passengers.

To Mrs. Jones we say Ẹ ku afojuba.

---

**HARVEST THANKSGIVING SERVICE.**

The Harvest Thanksgiving Service will be held in the African Church Cathedral (Bethel) tomorrow the 9th December, 1928, at 3.00 p.m. The Rt. Rev. N. Ọnatolu will preach the Harvest Sermon.

This will be the first Harvest Thanksgiving Service ever held in the New Edifice after Dedication. We congratulate Town Councillor J. Bagan Benjamin, C.E., A.M.I.C.E., as an Architect and Designer of this magnificent Cathedral.

OLUṢAKIN.

---

IKU MBẸ.

Gbukẹ ni a gbọ Ikn aya ọgbẹni wa Mr. Oseni Sarumi ẹgbon Mr, Sadiku Sarumi ti Mọlade Street Lagos ni ile rẹ—ni ọjọ Wednesday ọsẹ to kẹja 28/11/28 ki Oluwa fẹri ji.

---

WHO IS RESPONSIBLE? DIRECTOR OF WATER SUPPLY OR TOWN COUNCIL?

We noticed the water pipe erected at Onibudo Street Lagos, partially linked to a building known us 31, Onibudo Street Lagos, will put the building in jeopardy as the area in question very dampy and the said house in some years to come will not be in a dilapidating state?

With due deference we think a little more shift to few yards off will put this building in a proper state.

(THE STINKING STREETS)
IBOMỌ AND ISALẸAGBẸDẸ STREETS.

Why Town Council overlook these two Streets? Are they not among Municipal areas of Lagos?

## ADDRESS DELIVERED BY

MR. N. M. A. JOHNSON OF LAGOS,

West Africa, at a meeting of the Young Christians Association Sunday School, Metropolitan Tabernacle.

---

SUBJECT:—*Precious Promises.*

**Part I.**

PROMISES AND PROPHECIES

"One lot one title shall in no wise pass from the law, till all be fulfilled"—Mathew v. 18. (portion of verse 18.)

Christ referred here primarily to the promises and prophecies of the Old Testament. There are thousands of blossoms on the trees in the spring time that never become fruits, but there are no lost blossoms on the Old Testament tree. The exact fulfilment of prophecy is an irrefutable evidence of Christianity. But the assurance of these words refers also to every promise of the Scripture. Not the smallest of these shall ever fail any one who trusts them. "No word he hath spoken shall ever be broken." Every pledge God has made he will surely keep. Whenever we find a divine word we may lay hold of with perfect confidence, and know that we are clinging to a rock that never can be shaken. "For the mountains shall depart, and the hills be removed, but my kindness shall not depart from thee, neither shall the covenant of my peace be removed, saith the Lord that hath mercy on thee."

This is true also of the divine threatenings against sin. Not one of these shall fail to be accomplished upon those who reject God's words of grace and mercy, Christ said, "He that believeth on the Son hath everlasting life," and that word will prove true to everyone who receives it. But he said also in the same sentence, "He that beleiveth not the Son shall not see life, but the wrath of God abideth on him," and this word shall just as surely be fulfilled as the other. In these days when so many people hold loose views of God's Holy Word, it is well that we fix it deeply in our minds that whatever God says in the Holy Scriptures he says with authority—that his promises are sure as his own eternity, and that every sentence of his is absolutely irrepealable, "Only Words," we sometimes say, as if words were unreal and unsubstantial, but the words of God are more real, and more substantial than even earth's great mountains.

(*To be continued.*)

## Use Yaro for your baby!

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## Increased health for 3/- only.

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## A chance for female sufferers.

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc 1/- and 1/6d per bottle.

### Anti-Gon Pills.

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills—a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
109, Griffith Street, Ebute Metta.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq,
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist*,
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu ię mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

# HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ oriṣiriṣi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si lun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantẹnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by A. Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.